Nje ẹ mọ nnkan ti Oluwa yin sọ?” Wọn sọ pé: Ọlọhun ati ojisẹ rẹ ni wọn ni imọ julọ, o sọ pe: “O n bẹ ninu awọn ẹru Mi ẹni ti o ji ni onigbagbọ ati ẹni tí o ji ni alaigbagbọ

Lati ọdọ Zaid bn Khalid Al-Juhaniy- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pe: Ojisẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ki irun asunbaa fun wa ni Hudaibiyah lẹyìn ojo ti o rọ ni òru, lẹyìn tí ó kírun tán, o kọju si awọn eniyan, o sọ pe: “Nje ẹ mọ nnkan ti Oluwa yin sọ?” Wọn sọ pé: Ọlọhun ati ojisẹ rẹ ni wọn ni imọ julọ, o sọ pe: “O n bẹ ninu awọn ẹru Mi ẹni ti o ji ni onigbagbọ ati ẹni tí o ji ni alaigbagbọ, ẹni tí ó bá sọ pé: Wọ́n rọ òjò fun wa pẹlu ọla Ọlọhun ati aanu Rẹ, ìyẹn ni ẹni tí ó gbagbọ ninu Mi ti o si ṣe aigbagbọ si ìràwọ̀, ṣugbọn ẹni tí o ba sọ pe: Pẹ̀lú ìràwọ̀ bayii bayii, ìyẹn ni ẹni tí o ṣe aigbagbọ ninu Mi, ti o wa ni igbagbọ ninu ìràwọ̀”.

[O ni alaafia] [Ohun ti wọn fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ki irun asunbaa ni Hudaibiya- oun ni oko kan ti o sunmọ Mẹka- lẹyin ti ojo rọ ni alẹ yẹn, Igba ti o salamọ ti o ki irun rẹ tan o doju kọ awọn eniyan, o si bi wọn pe: Nje ẹ mọ nnkan ti Oluwa yin- Alagbara ti O gbọnngbọn- sọ? Wọn da a lohun pe: Ọlọhun ati Ojisẹ Rẹ ni wọn ni imọ julọ, O sọ pe: Dajudaju Ọlọhun ṣàlàyé pe awọn eniyan pin si meji nigba ti ojo ba rọ: Ipin kan ti o ni igbagbọ ninu Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga-, ati ipin ti o jẹ alaigbagbọ ninu Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga-, Ṣugbọn ẹni ti o sọ pe: Wọn rọ ojo fun wa pẹlu ọla Ọlọhun ati ikẹ Rẹ, ti o fi riro ojo ti sọ́dọ̀ Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga-; ìyẹn ni olugbagbọ ninu Ọlọhun Ọba Aṣẹ́dá Aṣeyiowuu ninu aye, o si jẹ alaigbagbọ si irawọ. Ṣugbọn ẹni ti o ba sọ pe: Wọn rọ ojo fun wa pẹlu irawọ bayii bayii; ìyẹn ni alaigbagbọ ninu Ọlọhun, olugbagbọ ninu irawọ, o si jẹ aigbagbọ kekere nigba ti o ṣe afiti riro ojo si ara irawọ; ati pe Ọlọhun ko ṣe e ni okunfa ti sharia tabi ti kadara, Ṣugbọn ẹni ti o ba ṣe afiti riro ojo ati nnkan ti o yàtọ̀ si i ninu awọn ìṣẹ̀lẹ̀ ori ilẹ si ara lilọ-bibọ àwọn ìràwọ̀ nibi yíyọ wọn ati jijabọ wọn, ti o n ni adisọkan pe oun ni ẹni ti o n ṣe e gangan, o ti jẹ alaigbagbọ ni aigbagbọ ti o tobi.


النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY


لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC
E-Da'wah Committee